# MAY 2021

**Agbára Gbọ́dọ̀ pàrọ̀ ọwọ́**

**ORIN:**

**<u>Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA</u>**

1. Àwọn agbára tí wọ́n ti yàn láti ríi pé mo dí ìlú mọ̀ọ́ká nípaṣẹ̀ àjálù, o kìí ṣe olùṣẹ̀dá mi, òpin dé bá ọ lónìí, kú, ní orúkọ Jésù.
2. Àwọn àjèjì òkùnkùn tó ń ṣe ibi lòdì sí mi, kìnníún ẹ̀yà Júdà, farahàn nínú ìbínú rẹ lónìí kí o sì run wọn dójú ikú, ní orúkọ Jésù.
3. Àwọn ọmọ òkùnkùn tí wọ́n ní ẹ̀rín máa dí ohun èèwọ̀ fún mi, gbọ ọ̀rọ̀ Olúwa, òpin máa dé bá yin ín lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Agbára yówù tó ti sọ ara rẹ̀ di èrùjẹ̀jẹ̀ nínú ayé mi, agbára tó pa Goliath máa pa ọ run lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Agbára tó lo òṣì àti ìníra láti dá àwọn òbí mi dúró, n kò kìí ṣe ìjẹ rẹ, kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Májẹ̀mú ikú yówù tí wọ́n yàn láti dẹ́rù ba ìwàláàyè mi , túká nípa iná, ní orúkọ Jésù.
7. Àwọn agbára tó fẹ́ kí ń rìn nínú isà okú, o máa kú lójijì lónìí, ní orúkọ Jésù.

**<u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ – ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍÍDÌ 91</u>**

1. Ọlọ́run, dìde, kí o sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí òkè iná àti ìṣẹ́ ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí òkè iná àti iṣẹ́ ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Àwọn agbára tó ń làkàkà láti borí ogun lòdì sí mi, idà Ọlọ́run, lù wọ́n dójú ikú, ní orúkọ Jésù
4. Àwọn agbára tó kórira mi àti ohun tí mo fẹ́ dà, parí, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn agbára tó ń lépa mi ní ọ̀nà ikú, kú dípò mi, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti pa iṣẹ́ ọwọ́ mi, gba ìparun, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ẹ̀mí alárìnkiri nínú àdúrà, mo gbé ọ dè kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**ORIN DÁFÍDÌ 9:2** Èmi ó yọ̀, èmi yóò sì ṣe inú dìdùn nínú rẹ, èmi yóò sì kọrin ìyìn sí orúkọ rẹ, ìwọ ọ̀gá-ògo jùlọ.

**ÌFAHÀN 3:5** Ẹnití ó bá ṣẹ́gun, òun náà ni a ó fi aṣọ funfun wọ̀: èmi kì yóò pa orúkọ rẹ rẹ́ kúrò nínú ìwé ìyè, ṣùgbọ́n "èmi yóò jẹ́wọ́ orúkọ rẹ̀ níwájú Baba mi, àti níwájú àwọn áńgẹ́lì rẹ̀.

**1TÍMÓTÉÙ 6:12** Máa ja ìjà rere ti ìgbàgbọ́, di ìyè àìnípẹ̀kun mú nínú èyítí a gbé pè ọ́ sí, tí ìwọ sì ṣe ìjẹ́wọ́ rere níwájú ẹlẹ́rìípúpọ̀.

**1 PÉTÉRÙ 5:8** Ẹ máa wà ní àìrékọjá, ẹ máa sọ́ra: nítorí èṣù ọ̀tá yín, bíi kìnnìún tí ń ké ramúramù, ó ń rìn káàkiri, ó ń wá ẹni tí yóò pajẹ kiri.

**Orin Dáfídì 103:5** Ẹnití ó fi ohun dídára tẹ́ ọ lọ́rùn: bẹ́ẹ̀ ni ìgbà èwe rẹ̀ di ọ̀tun bíi ti idì.

**NÚMÉRÌ 13:30** Kálẹ́bù si pa àwọn ènìyàn lẹ́nu mọ́ níwájú Mósè, ó sì wí pé, Ẹ jẹ́ kí á gòkè lọ lẹ́ẹ̀kan, kí á sì gbà á; nítorí pé àwa le ṣẹ́ ẹ.

**LÚKÙ 11:22** Ṣùgbọ́n nígbà tí ẹni tí ó lágbára jù ú bá kọlù ú, tí ó sì ṣẹgun rẹ̀, a gbà gbogbo ìhámọ́ra rẹ̀ tí ó gbẹ́kẹ̀lé lọ́wọ́ rẹ̀, a sì pín ìkógun rẹ̀.

**ORIN DÁFÍDÌ 35:27** Jẹ́ kí wọn kí ó máa hó fún ayọ̀, kí wọn kí ó sì máa ṣe inú-dídùn, tí ń ṣe ojú-rere sí òdodo mi: lóòótọ́ kí wọ́n kí ó má a wí títí pé, OLÚWA ni kí á máa gbéga, tí ó ní inù-dídùn sí àlàáfíà ìránṣẹ́ rẹ̀.

**SEFANIAH 3:17** OLÚWA Ọlọ́run rẹ lí agbára lí àarin rẹ̀; yóò gba ni là, yóò yọ̀ lí orí rẹ fún ayọ̀; yóò sinmi nínú ìfẹ́ rẹ̀, yóò fi orin yọ̀ lí orí rẹ.

**FILIPPI 4:4** Ẹ máa yọ̀ nínú Olúwa nígbà gbogbo: mo sì tún wí, Ẹ máa yọ̀.

**ORIN DÁFÌDÌ 94:19** Nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìbìnújẹ́ mi nínú mi, ìtùnú rẹ lí ó ń mú inú mi dùn.

**ISAIAH 61:10** Èmi ó yọ̀ gidigidi nínú OLÚWa , ọkàn mi yóò yọ̀ nínú Ọlọ́run mi; nítorí "ó ti fi agbádá ìgbàlà wọ̀ mi, ó ti fi aṣọ òdodo bò mí, gẹ́gẹ́ bí ọkọ ìyàwótí íṣe ara rẹ̀ lọ́ṣọ̀ọ́, àti bí ìyàwó ti ìfi ohun ọ̀ṣọ́ ṣe ara rẹ̀ lọ́ṣọ̀ọ́.

**JOHANNU 16:24** Títí di ìsinsin yìí ẹ kò tî béèrè ohunkóhunlí orúkọ mi: ẹ béèrè, ẹ ó sì rí gbà, kí ayọ̀ yín kí ó le è kún.

**ORIN DÁFÍDÌ 32:7** Ìwọ ni ibi ìpamọ́ mi: ìwọ yóò pa mí mọ́ kúrò nínú iṣẹ́; ìwọ yóò fi orin ìgbàlà yí mi ká à kiri.